UK Health Security Agency

NHS

# Ohun tí o yẹ ko retí lẹ́yìn **gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19**



## Ìwífún fún àwọn ènìyàn tó sẹ̀sẹ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19

Ṣe ìwádìí síi ní nhs.uk/CovidVaccine

# Àwọn Àkóónú

Kíni àwọn ìdíjú?

Mo ti gbọ wipe abẹ́rẹ́ àjẹsára le fa nkan osu segesege tabi isun ẹjẹ airotẹlẹ?

Kini ki nṣe bi mọ ba ni ifoya nipa awọn aami aarun?

Njẹ awọn idiju lile miiran wa?

Njẹ mo le duro fun isẹju mẹẹdogun (15) lẹyin abẹ́rẹ́ àjẹsára mi?

Igbawo ni mo le bada lọsi awọn isẹ oojọ?

Se abẹrẹ ajẹsara naa daabobo mi?

**Jọwọ ka iwe iwifun pelebe ọja naa fun alaye sii lori abẹ́rẹ́ àjẹsára rẹ, pẹlu awọn idiju to seeṣe, nipa wiwa Yellow Card Coronavirus.**

**O tun le jábọ̀ àwọn ìdíjú abẹ́rẹ́ àjẹsára tí o furasí lori oju-ewe ayelujara kanna tabi nipa gbigba apuu Kaadi Yellow (Yellow Card app).**

**yellowcard.mhra.gov.uk**

**Awọn eniyan ti wọn ni ewu awọn idiju coronavirus julọ (COVID-19) ni a ti fun ni abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19. Iwe pelebe yii nsọ ohun ti ó nilo lẹyin ti o ba gba abẹrẹ ajẹsara rẹ.**

## Kíni àwọn ìdíjú??

Bíi gbogbo oogun, abẹrẹ ajẹsara le fa awọn idiju. Ọpọ awọn nkan wọnyi ko le kosi ni pẹ, kii si ṣe gbogbo eniyan lo ni wọn. Awọn idiju abẹrẹ ajẹsara COVID-19 to wọpọ bẹrẹ laarin ọjọ kan o si le pẹ fun ọjọ diẹ.

Awọn wọnyi pẹlu:

- Nininíní ìnira kan, ìmọ̀lára ara wíwo àti ara rírọ̀ ní apá níbití o ti gba àbẹ́rẹ́
- ìmọ̀lára rírẹ̀
- orí fífọ́, ara riro ati otutu

O tun le ni awọn aami aarun to jọ ọfinkin pẹlu awọn isẹlẹ gbigbọn fun ọjọ kan tabi meji. Ẹwẹ, ara gbigbona tun le jẹ pe o ni COVID-19 tabi aranmọ miiran (ri imọran lori oju-ewe 4). O le sinmi kí o sì lo òògùn paracetamol (tẹ̀lé ìmọ̀ràn abẹ́rẹ́ nínú àpamọ́ náà) láti ràn ọ́ lọ́wọ́ kí o gbádùn dáradára.

Idiju ti ko wọpọ ni awọn isun wiwu ni abiya tabi ọrùn ni ẹgbẹ apa kanna nibiti o ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára. Eyi le pẹ to bii ọjọ mẹwa, sugbọn bi o ba pẹ jubẹlọ ri dokita rẹ. Bi o ba to fun ọ lati ya aworan inu ara ni awọn ọsẹ diẹ lẹyin abẹ́rẹ́ àjẹsára, lẹyin naa o gbọdọ sọ iyẹn nigbati o ba lọ.

## Mo ti gbọ wipe abẹ́rẹ́ àjẹsára le fa nkan osu segesege tabi isun ẹjẹ airotẹlẹ?

Awọn isoro nkan osu ma n wọpọ gidigidi o si le waye nipa orisirisi okunfa pẹlu wahala ati awọn aisan aitọjọ miiran.

Awọn eniyan le ni iriri lile ju awọn nkan osu deede lọ ni osu naa abi nkan lẹyin abẹ́rẹ́ àjẹsára. Nigbati awọn eniyan kan ba ti jabọ awọn iyatọ iyooku si awọn nkan osu lẹyin abẹ́rẹ́ àjẹsára, kosi aridaju wipe ayọrisi abẹ́rẹ́ àjẹsára ni eyi.

## Kini ki nṣe bi mọ ba ni ifoya nipa awọn aami aarun?

Àwọn ààmì àìsàn kìí saba pẹ́ tó ọ̀sẹ̀ kan. Bí àwọn ààmì àìsàn rẹ bá fẹ́ burú tàbí bí àyà bá ńfò ọ́, pe NHS 111. Bí o ba ngba imọran lati ọdọ dokita tabi nọọsi kan, rii daju wipe o sọ fun wọn nipa abẹ́rẹ́ àjẹsára rẹ (fi kaadi abẹ́rẹ́ àjẹsára han wọn) ki wọn le ṣe ayẹwo rẹ daradara.

O tun le jábọ̀ àwọn ìdíjú abẹ́rẹ́ àjẹsára àti òògun tí o furasí nípasẹ̀ Ètò Yellow Card. O le ṣe eleyi lori ayekujara nipa wiwa Yellow Card tabi gbigba Yellow Card app lori foonu (jọwọ wo oju-ewe 2)



## Njẹ awọn idiju lile miiran wa?

Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ọkàn wíwú (tí à ńpè ní myocarditis àbí pericarditis) ti ko wọpọ ni wọ́n ti jábọ̀ lẹ́yìn àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 ti Pfizer àti Moderna. Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ wọ̀nyí ni a ti ń sábà rí nínú àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin àti láàrin ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọjọ́ gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn tó sẹlẹ̀ sìí ti ṣe dáradára wọ́n sì ti gbádùn kíákíá ní titẹle ìsinmi àti àwọn ìtọ́jú pẹ́pẹ́pẹ̀ẹ́.



**O gbọ́dọ̀ wá ìmọ̀ràn ìlera ní kíákíá bí o bá ní ìrírí:**

- ìrora àyà
- èémí kúkúrú
- ìmọ̀lára níní yíyáralu ọkàn, àìfọkànbalẹ̀ tàbí ọkan lílù pìpì

## Ṣe ki nduro fun iseju meedogun (15) leyin abẹ́rẹ́ àjẹsára mi?

Nigbati a kọkọ lo awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára Pfizer àti Moderna, awọn eniyan duro lẹyin fun ayẹwo fun iseju meedogun (15) leyin abẹ́rẹ́ àjẹsára. Latari awọn atunbọtan aibaramu ti ko pọ, awọn eniyan pẹlu itan aibaramu lile tabi awọn to ni atunbọtan si abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 too ti gba tẹlẹ ni lati duro fun akoko yii.

Nitori ewu didaku, ẹwẹ, ẹnikẹni ko gbọdọ wakọ fun o keere tan iseju meedogun (15) lẹyin gbigba abẹ́rẹ́ àjẹsára.

## Igbawo ni mo le bada lọsi awọn iṣẹ oojọ?

O gbọdọ le bẹrẹ awọn iṣẹ to ṣe deede fun ọ gẹgẹbi o ṣe gbadun si. Bi apa rẹ ba ni egbò, o le nira fun ọ lati gbe nkan wuwo. Bi ara rẹ ko ba ya tabi o rẹ ọ, o gbọdọ sinmi ki o si yago fun lilo ẹrọ tabi wa ọkọ.

## Se abẹrẹ ajẹsara naa daabobo mi?

Awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 too ti gba ti s’afihan dindin aaye irora ti aarun COVID-19 lile ni ku.

O le to ọsẹ diẹ lati igba abẹ́rẹ́ akọkọ fun ara rẹ lati ni aabo. Ara rẹ gbọdọ bẹrẹ sii ya ni kiakia (lẹyin ọjọ diẹ) lẹyin eyikeyi awọn alekun abẹrẹ. Bíi gbogbo òògùn, kòsí abẹ́rẹ́ àjẹsára tó péye pátápátá, nitorina o gbọdọ tẹsiwaju lati maa ṣe akiyesi olóye lati jago fun aranmọ. Àwọn ènìyàn kọọkan si tun le ní COVID-19 biotijẹpe wọn gba abẹ́rẹ́ àjẹsára, sùgbọ́n eyi kò gbọ́dọ̀ le.

Abẹ́rẹ́ àjẹsára naa o le fún ọ ni aarun COVID-19, agbakun rẹ yoo din aaye siṣe aisan lile ku.




**Pa kaadi rẹ mọ lai l’ewu.**
**Iwọ naa le yẹ Apuu NHS wo.**

## Gbigba abẹ́rẹ́ àjẹsára, nṣe iranlọ́wọ lati daabobo awọn ti ko lagbara

**Bi o ba nilo iwifun siwaju sii lori gbigba abẹrẹ ajẹsara COVID-19, jọwọ ṣe abẹwo si:**

www.nhs.uk/conditions/coronavirus-covid-19/coronavirus-vaccination/coronavirus-vaccine/




© Crown copyright 2023
V7. 3M MAR 2023 (APS). Product Code: COV23WTYO Yoruba
UK Health Security Agency gateway number: 2022824

Ìwé pélébé yìí wa laarọwọto ní braille, gẹgẹbi fidio BSL kan, atẹjade nla, gẹgẹbi ẹda to rọrun lati ka, ti a tumọsi ede to ju 26 lọ lati beere lori www.healthpublications.gov.uk tabi pe 0300 123 1002